# Ìyísódì Abèjì Nínú Ẹ̀ka-Èdè Ifẹ̀

*Adékúnlé, Moses A., PhD*

## Àṣamọ̀

*Ọ̀kan lára kókó tí ìmọ̀ ìjìnlẹ̀ káríayé fidíí rẹ̀ múlẹ̀ ni pé bí ọ̀rọ̀ ìyísódì méjì bá wa nínú ìhun kan náà, ìtumọ̀ ìjọ́hẹn ni irú ìhun bẹ́ẹ̀ yóò ni. Èrò yìí, èyí tí ìmọ̀ ẹ̀kọ́ ìsirò jẹ́ ìpìlẹ̀ rẹ ni a rii pé ìmọ̀ ẹ̀dá-èdè kín lẹ́yìn. Nínú ẹ̀ka èdè Ifẹ̀, a kíyèsíí pé ẹ̀yà méjì ni àbájàde irú ìgbẹ́ṣẹ̀ ìyísódì abèjì máa ń jẹ́. Ní ìgbà mìíràn tí a bá ṣe àmúlò wúnrẹ̀n atọ́ka ìyísódì méjì, àbájàde ìtumọ̀ gbólóhùn bẹ́ẹ̀ yóò jẹ́ ìtumọ̀ ìjọ́hẹ̀n, bí àpẹẹrẹ É è ṣe ghí <u>Ol</u>ú ù ghà (Ìyẹn ni pé olú ghá. Ẹ̀wẹ̀, ìgbà mìíràn, ẹyọ wúnrẹ̀n atọ́ka ìyísódì kan ṣoṣo ni yóò fára hàn nínú ìhun gbólóhùn ṣùgbọ́n tí ó jẹ́ pé ìtumọ̀ ìjọ́hẹn ní irú gbólóhùn bẹ́ẹ̀ yóò ní. Ohun tí a kíyèsí ni pé ọ̀kan nínú ọ̀rọ̀-orúkọ tí ó súyọ nínú ìhun náà jẹ́ ọ̀rọ̀ orúkọ onítumọ̀ òdì, bí àpẹẹrẹ, àjẹ̀mọ, àsetì, àghámọ, òdì, àjẹ̀kù abbl. A fura pé mọ,tì, mọ, dì, kù, tí wọ́n jẹ́ ọ̀rọ̀-ìṣe tàbí ẹ̀pọ́n ìṣe tí wọ́n jẹ́ ọ̀pọ̀ nínú ìlànà ìṣẹ̀dá àwọn ọ̀rọ̀ orúkọ yìí ni wọ́n jẹ́ ọ̀rọ̀-ìṣe onítumọ̀ òdì. Bí àpẹẹrẹ, mé èjẹ àjẹ<u>kù</u>, A à se iṣẹ́ náà ní àsetì. Ìtumọ̀ ìjọ́hẹn ni àwọn ìpèdè méjèèjì yìí ní. Ohun tí à ń fidìí rẹ̀ múlẹ̀ ni pé ìtumọ̀ ìjọ́hẹn tí àwọn gbólóhùn méjèèjì yìí ni nínú ẹ̀ka-Ifẹ̀ rú òfin ìmọ̀ ẹ̀dá-èdè tí ó ń retí pé kí wọn ní ìtumọ̀ òdì. Àṣamọ̀ tí àbájàde yìí ń pa lásamọ̀ ni pé ìmọ̀ ẹ̀kọ́ ìṣẹ̀dá àwọn ọ̀rọ̀ orúkọ nínú èdè Yorùbá tún ń fẹ́ ìtẹ̀síwájú. Ìlànà ìmọ̀ ìṣàpèjúwè èyí tí elédèni gẹ́gẹ́ bí ìmọ̀ ọgbọ́n ìbílẹ̀ ni a lò nínú iṣẹ́ ìwádìí yìí.*

*Àwọn kókó ọ̀rọ̀ àyẹ̀wò:* *ìtumọ̀ òdì, ọ̀rọ̀, àpólà kíkún, ìpìlẹ̀, ìpele.*

## Ìfáàrà

Ìgbẹ́ṣẹ̀ ìyísódì abèjì jẹ ọ̀kan lára ọ̀nà ìṣàmúlò òfin ajẹmọ ìmọ̀ ìsirò nínú ìmọ̀ ẹ̀dá-èdè. Ìmọ̀ ìjìnlẹ̀ èrò nípa ìyísódì abèjì ni pé tí atọ́ka ìyísódì méjì bá jẹyọ nínú ìhun gbólóhùn kan náà, ìtumọ̀ ìjọ́hẹn ni irú gbólóhùn bẹ́ẹ̀ yóò mú jáde. Tí a bá fojú ìtumọ̀ wò ó bá yìí nínú ẹ̀ka-èdè Ifẹ̀, a lè sọ pé orísì ìyísódì abèjì méjì ló wà nínú ẹ̀ka-èdè Ifẹ̀. Àwọn náà ni:

a. Ìyísódì abèjì onítumọ̀ ìjọ́hẹn
b. Ìyísódì abèjì onítumọ̀ òdì

Ìyísódì abèjì onítumọ̀ ìjọ́hẹn ni a tún lè pín sí orísì méjì. Àwọn náà ni:

1. Ìyísódì gbólóhùn oní-wúnrẹ̀n atọ́ka ìyísódì méjì.
2. Ìyísódì gbólóhùn ọ̀rọ̀-orúkọ onítumọ̀ òdì.

A ó gbìyànjú láti jíròrò lórí àwọn ẹ̀yà gbólóhùn ìyísódì méjèèjì *a* àti *b* lẹ́kùnrẹ́rẹ́ nínú ẹ̀ka-èdè Ifẹ̀ nínú pépè yìí. Saájú èyí, a fẹ́ pàátó lórí tíọ́rì tí a fẹ fi ṣe àtẹ̀gùn fún àlàyé wa. Tíọ́rì tí a fẹ́ lò ní ẹ̀yà tíọ́rì Gírámà Ìhun Gbólóhùn Alákọ̀ọ̀tán ti Cann (1986) dábàá. Tíọ́rì yìí ni Fábùnmi (2006b) dábàá àgékúrú GÍGA fún.

## Àbá Cann (1986) Lórí tíọ́rì GÍGA

Ẹ̀yà tíọ́rì GÍGA tí a gbé iṣẹ́ wa yìí lé lórí ni èyí tí Cann (1986) ṣe agbátẹrù rẹ̀. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé iṣẹ́ rẹ̀ àti ti Gazdar *et al* (1985) jọra dé àyè kan, síbẹ̀ òṣùwọ̀n tí àwọn méjéèjì lò nínú àtúpalẹ̀ wọn yàtọ̀ sí ara wọn díẹ̀. Gazdar àti àwọn ẹlẹ́gbẹ́ rẹ̀ lo ìlànà àwòrán-atọ́ka igi onípele méjì nígbà ti Cann (1986) lo ìlànà àwòrán-atọ́ka igi onípele kan ṣoṣo.

Lójú Gazdar *et al* (1985), ìsọ̀rí-ọ̀rọ̀ kan jẹ àpapọ̀ àbùdá tó ń ṣàfihàn orúkọ wọn àti kókó iṣẹ́ tí wọn ń ṣe nínú ìhun. "*Mo*" tó jẹ́ ARK ẹnìkínní aṣolùwà ló ní àwọn àbùdá bí i:

1

$$\left\{\begin{array}{c|c} \text{IPL} & 2 \\ \text{AR} & + \\ \text{IṢ} & - \\ \text{ẸN} & 1 \\ \text{ỌPỌ̀} & - \\ \text{OR} & + \end{array}\right\}$$

Gazdar et al (1985) ṣe àmúlò ìlànà onípele (IPL) méjì. Ohun tí (2) ń tọ́ka sí ni pé *Mo* bí fọ́nrán Ìhun nínú APOR, tún jẹ́ Ìhun àpólà tó jẹ́ ìpele méjì nínú ẹ̀hun àwòrán-àtẹ onígi. Gazdar *et al* (1985) kò sọ̀rọ̀ nípa àpínpẹ̀kun. Àlàyé àgbékalẹ̀ wọn lórí kókó ọ̀rọ̀ náà nìyí:

2. NP > [+N, -V, BAR 2]
   VP > [+V, -N, -SUBJ, BAR2]
   Ní báyìí, ẹ jẹ́ kí a wo èrò Cann (1986) lórí àbùdá ọ̀rọ̀ àti àpínpẹ̀kun

## Àbùdá Ọ̀rọ̀ àti Àpínpẹ̀kun

Lójú Cann (1986), a lè pín ìṣọ̀rí sí mẹ́rin. Èkíní ni ìsọ̀rí tí ó jẹ́ àpínpẹ̀kun tí ó sì jẹ́ pé ohun tí ó gàba lé lórí ju wúnrẹ̀n kan lọ. A ó pe eléyìí ni APX. Ìṣọ́rí kejì, kì í ṣe àpínpẹ̀kun ó sì ju wúnrẹ̀nkan lọ. A ó máa pe eléyìí ní XB. Ẹ̀kẹ́ta ni ìsọ̀rí tí ó jẹ́ àpínpẹ̀kun tí ó sì tún jẹ́ wúnrẹ̀n kan. A ó pe eléyìí ni XF (wo iṣẹ́ Adékúnlé 2018, Raji 2017, Adéníyì 2019 fún ẹ̀kúnrẹ́rẹ́ àlàyé). Bí àwọn ìpín mẹ́rẹ̀ẹ̀rin ṣe rí nìyí:

3. i. [<ÀPÍNPẸ̀KUN, + ><WÚNRẸ̀N, - >] APX (Èyí ni ìsọ̀rí tí ó jẹ́ àpínpẹ̀kun tí kì í ṣe wúnrẹ̀n kan ṣoṣo, bí àpẹẹrẹ, àpólà orúkọ, bàtà Olúkékeré tí ORX yóò jẹ gàba lé lórí)


   ii. [<ÀPÍNPẸ̀KUN, - ><WÚNRẸ̀N,- >] XB (ìsọ̀rí tí kì í ṣe àpínpẹ̀kun tí kì í ṣe wúnrẹ̀n kan, bí àpẹẹrẹ, àpólà orúkọ, ajá ọdẹ tí ó jẹ yọ nínú àpólà orúkọ mìíràn, ọmọ ajá ọdẹ. ORB ni yóò jẹ gàba lé ajá ọdẹ lórí nítorí pé kì í ṣe àpínpẹ̀kun kì í sìí ṣe wúnrẹ̀n kan.

   iii. [<ÀPÍNPẸ̀KUN, ><WÚNRẸ̀N, + >] XD (Èyí ni ìsọ̀rí tí kì í ṣe àpínpẹ̀kun tí ó sì jẹ́ wúnrẹ̀n kan ṣoṣo, bí àpẹẹrẹ, Olú nínú àdpólà orúkọ ilé Olú. ORD ni yóò jẹ gàba lé Olúlórí nítorí pé ó jẹ́ ọ̀rọ̀ kan kì í sìí ṣe àpínpẹ̀kun nínú ilé Olú.


   iv. [<ÀPÍNPẸ̀KUN, + ><WÚNRẸ̀N, + >] XF (Eléyìí Ni ìsọ̀rí tí ó jẹ́ àpínpẹ̀kun tí ó sì tún

jẹ́ wúnrẹ̀n kan, bí àpẹẹrẹ, Adé nínú gbólóhùn Adé sùn. ORF ni yóò jẹ gàba lé Adé lórí nínú gbólóhùn Adé sùn nítorí pé ó jẹ́ àpínpẹ̀kun ó sì jẹ́ wúnrẹ̀n kan. Tí a bá wá fi ìlànà àpínpẹ̀kun àti ọ̀rọ̀ yìí ya àwòrán-àtẹ onígi fún gbólóhùn yẹn, bí yóò ṣe rí nìyí:


4. (i) Adé sùn (Adé sun)




(ii) Adé ti fẹ́ ìyàgbó (Adé ti fẹ́ ìyàwó)




(iii) Ìyá Olú gba oghó ọbẹ̀ (Ìyá Olú gba owó ọbẹ̀)




Ní bá yìí, ẹ jẹ́ kí a bẹ̀rẹ̀ àlàyé lórí ìyísódì méjééjì. A ó rí i pé kò sí ìfipeleṣòfò kan-kan nínú àwòrán-àtẹ onígi wọ̀nyí.

1. Ìyísódì abèjì onítumọ̀ ìjọ́hẹn

Gẹ́gẹ́ bí a ti mẹ́nu bá a saájú, orísì ẹ̀yà gbólóhùn ìyísódì yìí méjì ló wà. Àwọn náà ni:

a. Ìyísódì gbólóhùn oní-wúnrẹ̀n atọ́ka ìyísódì méjì.

b. Ìyísódì gbólóhùn ọ̀rọ̀-orúkọ onítumọ̀ òdì.

A ó bẹ̀rẹ̀ àlàyé lórí ìyísódì gbólóhùn oní-wúnrẹ̀n atọ́ka ìyísódì méjì.

A. Gbólóhùn oní-wúnrẹ̀n atọ́ka ìyísódì méjì


Èyí máa ń wáyé nígbà tí gbólóhùn kíkún kan bá ni atọ́ka ìyísódì orísi méjì nínú ìhun èyí tó mú kí gbólóhùn náà yọrí sí ìtumọ̀ ìjọ́hẹn. Bí àpẹẹrẹ:

i. Ighán àn gbọdọ̀ mọ́ọ̀ ghá (wọ̀n ò gbọ́dọ̀ máà wá).


ii. Ọmọ nì ìn bá mọ́ọ̀ kú (ọmọ yẹn kò bá máà kú).

Ìtumọ̀ gbólóhùn 'i' ni pé àwọn ẹni náà wá; ìtumọ̀ gbólóhùn 'ii' ni pé ọmọ náà kú; A lè ṣe àtúpalẹ̀ àwọn gbólóhùn yìí pẹ̀lú àwòrán atọ́ka igi bíi ti ìsàlẹ̀ yìí:

4(i). Ighán àn gbọdọ̀ mọ́ọ̀ ghá




(ii). Ọmọ nì ìn bá mọ́ọ̀ kú




A fi àmì ìràwọ̀ (*x x*) méjì sàmì sí àwọn atọ́ka-ìyísódì méjèèjì tó jẹyọ nínú gbólóhùn kọ̀ọ̀kan. Ní báyìí, a fẹ́ jíròrò lórí ìpínsí ẹ̀yà ìyísódì Abèjì kejì onítumọ̀ Ìjọ́hẹn.

b. Gbólóhùn Ọ̀rọ̀ Orúkọ Onítumọ̀ Òdì

Ìwádìí tí a ṣe nínú iṣẹ́ yìí fi hàn pé àwọn ìsọ̀rí ọ̀rọ̀ orúkọ kan wà nínú ẹ̀ka-èdè Ifẹ̀ tó jẹ́ pé ìtumọ̀ òdì ni wọ́n ní. Ohun tó mú kí a fura sí àwọn ọ̀rọ̀-orúkọ yìí ni pé ní gbogbo ìgbà tí atọ́ka-ìyísódì bá jẹyọ nínú ìhun gbólóhùn tí wọ́n wà, ìtumọ̀ ìjọ́hẹn ní irú gbólóhùn bẹ́ẹ̀ máa ń mú jáde. Ní àfikún, a wòye pé àwọn ọ̀rọ̀-orúkọ wọ̀nyí kì í ṣe ọ̀rọ̀-orúkọ ìbílẹ̀ ẹ̀ka-èdè náà. Ọ̀rọ̀-orúkọ aṣẹ̀dá ni wọn. Tí a bá fojú ìmọ̀ ìṣẹ̀dá-ọ̀rọ̀ wò wọ́n, a kẹ́fin pé ọ̀rọ̀-àpọ́nlé tàbí ọ̀rọ̀-ìṣe ni òpó tí ó jẹ́ mọ́fíìmù ìpìlẹ̀ tí a fi ṣẹ̀dá àwọn ọ̀rọ̀-orúkọ onítumọ̀ òdì yìí. Ìdí mìíràn tí a tún fi fẹ́ ṣàlàyé nípa irúfẹ́ àwọn gbólóhùn ìyisódì tí àwọn ọ̀rọ̀-orúkọ yìí ti jẹyọ ni pé ìtumọ̀ gbólóhùn tí wọ́n bá ti jẹyọ bá ti ìtumọ̀ àwọn gbólóhùn ìyísódì abèjì tí a kọ́kọ́ jíròro lé lórí mu. Díẹ̀ lára àwọn àpẹẹrẹ ọ̀rọ̀-orúkọ onítumọ̀ òdì ni wọ́n wà nínú àtẹ ìsàlẹ̀ yìí pẹ̀lú ìlò wọn nínú ìhun gbólóhùn nínú EDF.


5.

| Nọ | Ọ̀rọ̀-orúkọ onítumọ̀ òdì | Gbólóhùn ìyísódì tí a tí lowo ni EDF | Ìtumọ̀ gbólóhùn ìyísódì ní OED |
|---|---|---|---|
| i. | Òdì | Mẹ́ẹ̀ gwọ òdì asọ | Bí o ṣe tọ̀nà kí ń wọ aṣọ ni mo wọ̀ọ́ |
| ii. | Ìkùnà | Ìkùnà àn níí dé bá ọ̀rọ̀ ni | Ọ̀rọ̀ náà yóò yọrí sí rere |
| iii. | Ọ̀kùtà | Ọ̀kùtà aà níí gwọ ọjà rẹ̀. | Ọjà náà yóò já sí èrè. |
| iv. | Àgwátì | Ẹ́ ẹ̀ nigwá ire ní àgwátì | Ẹ ó máa ṣe àṣeyege |
| v. | Etì | Etì ì ní í bá ọ̀rọ̀ nò | Ọ̀rọ̀ náà yóò yọrí sí rere |


Irúfẹ́ àwọn ọ̀rọ̀-orúkọ onítumọ̀ òdì báyìí pọ̀. Lára àwọn mìíràn tó kù ni i àbùkù, àkùdé, àtadí, àpatì, àsọtì, àṣetì, àjẹ̀mọ, àghámọ, àrímọ, àsọtì àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.

Ní bá yìí, a ó gbìyànjú láti ya àwòrán-atọ́ka igi díẹ̀ pẹ̀lú tíọ́rì tí a lò nínú iṣẹ́ ìwádìí yìí láti ṣe àfihàn àtúpalẹ̀ àwọn ìhun gbólóhùn ìyísódì tí àwọn ọ̀rọ̀-orúkọ wọ̀nyí ti jẹ yọ nínú àtẹ tí a yà sókè. Bí àpẹẹrẹ:


6. (i) Mẹ́ ẹ̀ gwọ òdì èghù





(ii) Ìkùnà àn níí dé bá ọ̀rọ̀ náà




(iii) Ọ̀kùtà à níí gwọ ọjà rẹ̀



(iv) Ẹ́ ẹ̀ níí gwá ire ní àghátì





2. Ìyísódì Abèjì Onítummọ̀ Òdì

Gẹ́gẹ́ bí a ti mẹ́nu bá a sáájú, ìlò atọ́ka ìyísódì méjì nínú gbólóhùn kan ṣọ̀ṣọ máa ń mú ìtumọ̀ ìjọ́họn jáde. Ṣùgbọ́n ní ìgbà mìíràn nínú ẹ̀ka-èdè Ifẹ̀, a rí i pé ìlò atọ́ka ìyísódì méjì, máa ń mú ìyísódì wá. Bí àpẹẹrẹ:

i. É è è é se ghí Olú ghá (kò kì í ṣe pé Olú wá)

ii. É è é se Kọ́lá kọ́ ni ó dé (kì í ṣe Kọ́lá de kọ́ ni ó dé).

Tí a bá fojú ìtumọ̀ wo àwọn gbólóhùn méjèèjì yìí, gbólóhùn kínní ń tẹnu mọ́ ọ pé *Olú ò wá*, nígbà tí gbólóhùn kejì n tẹnu mọ́ ọ pé *Kọ́lá ò dé*. Ohún tí a kíyè sí nípa irúfẹ́ àwọn ìpèdè báyìí ni pé ọ̀kan nínú àwọn atọ́ka ìyísódì méjèèjì ló siṣẹ́ ìyísódì. Atọ́ka ìyísódì kejì ń sàfihàn ibá-ìṣẹ̀lẹ̀ atẹ́rẹ́rẹ́ èyí tó ń tẹnu mọ́ ìṣe atọ́ka ìyísódì kìíní. Kí àlàyé wa lè já gaara, a ó fi àwọn àwòrán-atọ́ka igi ìṣàlẹ̀ yìí ṣe àtúpalẹ̀ ìhun wọn *É è éé se ghí Olú ghá* (kò kì í ṣe pé Olú wá).




Kókó tí a fẹ́ fẹ̀ṣẹ̀ rẹ̀ múlẹ̀ ni pé:

i. *Kìí*kì í ṣe ẹyọ ọ̀rọ̀ kan; *kì* jẹ́ atọ́ka ìyísódì nígbà tí *í* jẹ wúnrẹ̀n atọ́ka ibá-ìṣẹ̀lẹ̀ bárakú atẹ́rẹrẹ.

ii. Kò tọ̀nà láti máa kọ *kìí* bí a ṣe máa ń kọ ọ́ tẹ́lẹ̀ bí kò ṣe *kì í* àtúnṣe yìí yóò lè jẹ́ kí a lè ṣe àfihàn ègé mọ́fíìmù aṣegírámà yìí lọ́tọ̀ọ̀tọ̀ lórí àwòrán atọ́ka-igi.

Àbá yìí kín èrò Awóbùlúyì àti Oyèláràn (2017) lórí àkọtọ́ ọ̀rọ̀ yìí lẹ́yìn. A fara mọ́ àbá àwọn Ọ̀jọ̀gbọ́n bíi Bámgbóṣé (1990) àti Owólabí (2011) pé *kì ní...* ní ìpìlẹ̀ *kì í...* nínú olórí ẹ̀ka-èdè Yorùbá.

8.




Ìdí tí a fi lo àmì láti ya *'kì ń'* sọ́tọ̀ ni pé a ti sàlàyé nínú àwọn iṣẹ́ wa mìíràn lórí bí *'un'* tàbí *'in'* ṣe jẹ́ mọ́fíìmù ìpìlẹ̀ fún kọ́ńsónàǹtì aránmúpè aṣesílébù nínú olórí ẹ̀ka-èdè Yorùbá. (wo Adékúnlé 2019b).

Ohún tí à ń sọ ní pàtó ni pé: A kò fara mọ́ èrò àwọn Ọ̀jọ̀gbọ́n Bámgbóṣé (1990), Awóbùlúyì (1998) àti Owólabí (2011) pé ìpajẹ ìró fáwẹ̀lì *i* ló sọ *ní* di *ń*. Irúfẹ́ àlàyé bá yìí ko se é gbára lé lọ gaara.

Àlàyé ohun tí à ń sọ nípa àbá titun *'un'* tàbí *'in'* fún mọ́fíìmù ìpìlẹ̀ kọ́ńsónàǹtì aránmúpè aṣesílébù (KAA) nì a lè ṣe àkàwé pẹ̀lú àwọn ẹ̀ka-èdè Yorùbá bí i mẹ́rin yìí

Ẹ̀ka-Èdè Kétu

9a. (i) Mò ún bọ̀

(ii) Mò ún gbọ́

(iii) Mò ún múlé

*(Ẹ̀ka-èdè Kétu ń lo un)*

Ẹ̀ka-Èdè Òǹkò

9b. (i) Mò ín bọ̀

(ii) Mò ín gbọ́n

(iii) Mò ín lọ sílé

*(Ẹ̀ka-Èdè Òǹkò ń lo in)*

Ẹ̀ka-Èdè Ìjẹ̀bú

9d. (i) Mò ḿ/ún wá a
(ii) Mì ḿ/ún gbọ́
(iii) Mò ḿ/ún lọ rúlé
*(Ẹ̀ka-Èdè Ìjẹ̀bú ń lo ḿ tàbí ún)*

Olórí Ẹ̀ka-Èdè Yorùbá

9e. (i) Mò ń bọ̀
(ii) Mò ń gbọ́
(iii) Mò ń lọ sílé
*(Olórí Ẹ̀ka-Èdè Yorùbá ń lo ń)*

Ẹ̀ka-Èdè Ifẹ̀

9ẹ. (i) Mọ mí bọ̀
(ii) Mọ mí gbọ́
(iii) Mọ mi relé
(Ẹ̀ka-Èdè Ifẹ̀ ń lo mí)

Nítorí náà, ohún tí à ń sọ báyìí ni pé Ẹ̀ka-Èdè Òǹkò àti Ẹ̀ka-èdè Kétu tì ń sọ ín tàbí un (Èyí tí a lérò pé ó jẹ́ ìpìlẹ̀ mọ́fíìmù kọ́ńsónàǹtì aránmúpè aṣesílébù (KAA); Ẹ̀-ka-èdè Ìjẹ̀bú àti Olórí ẹ̀ka-èdè Yorùbá ń sọ ẹ̀dà mọ́fíìmù kọ́ńsónàǹtì aránmúpè aṣesílébù 'm/n', nígbà tí ẹ̀ka-èdè Ifẹ̀ pa òfin ìbílẹ̀ èdè Yorùbá mọ́ pé, kò yẹ kí ìró tó dúró fún kọ́ńsónàǹtì aránmúpè gba àbùdá àmì ohùn (àbùdá yìí wà fún ìró fáwẹ̀lì nìkan). Èyí ló mú kí ẹ̀ka-èdè Ifẹ̀ gbé ìgbésẹ̀ àfikún i láti kúkú ṣọ mọ́fíìmù kọ́ńsónàǹtì aránmúpè aṣesílébù di odidimọ́fíìmù mí. A lérò pé àbá wa yìí kìí ṣe titun dà bí àrà. Àbá yìí fara pẹ́ ọ̀kan lára èrò Abraham (1958: xxii) pé:

10. Thus: un óòlọ = n̄ óò lọ *I shall go.*

In the same way, we have ún= ń

(i.e. N. Not N here) in the progressive:

Mó ń lọ = Mò ún lọ I am going: a ń lọ =

A ún lọ = we are going.

[Nítorí náà, un óò lọ yóò di n óò lọ (I shall go). Bákan náà, a ní un tó yí padà di n (b.a. kìí ṣe àpapọ̀ Ni ní àsìkò yìí) nínú ìlò ibá-atẹ́rẹrẹ:mò ń lọ yóò dí mò ún lọ(I am going); a ń lọ yóò di a ún lọ (we are going)].

11. Nínú iṣẹ́ Abraham (1958:xii) yìí, a lè ṣe àgékúrú èrò rẹ̀ báyìí:

i. N—> n tàbí m

ii. Un—> n tàbí m'

Tí a bá tèlé àbá *i,* ìbéèrè tí a gbọ́dọ̀ wá ìdáhùn sí ni pé báwo ni ọ̀rọ̀ gírámà *ni* ṣe ń yípadà di *mi* tàbí *m* nínú àwọn ẹ̀ka-èdè kan bí i ẹ̀ka-èdè Ìjẹ̀bú àti ẹ̀ka-èdè Ifẹ̀ láìwó ti ìró tó wà ní àyíká wọ́n. Tí a bá gba àbá ti 'ii', a ó nílò ọ̀pọ̀ àlàyé kí a tó

lè fìdí bí *un*ti ń yí padà di *n*,*m*, *ni*, tàbí *mí*. Láti yanjú ìsòro yìí ló mú kí a gbà *un/in* gẹ́gẹ́ bí i ìpìlẹ̀ mọ́fíìmmù aṣegírámà tó ń yí padà di kọ́ńsónàǹtì aránmúpè aṣesílébù nínú olórí ẹ̀ka-èdè Yorùbá àti àwọn ẹ̀ka-èdè Yorùbá mìíràn. A wòye pé àbá wa yìí nílò àlàyé díẹ̀ síi, èyí ni ó fà á tí a fi fẹ́ sàlàyé díẹ̀ nípa bí ìgbéṣẹ̀ yìí ti ń wáyé.

Àlàyé Díẹ̀ nípa Ìpìlẹ̀ *UN* tàbí *IN* fún Kọ́ńsónàǹtì Àránmúpè Aṣesílébù

Ní àkọ́kọ́, a fẹ́ kí a mọ̀ pé àlàyé yìí yóò ṣiṣẹ́ fún ìwádìí ìpìlẹ̀ mọ́fíìmù àfòmọ́ {òǹ-} àti {oń-} nínú mofọ́lọ́jì agbàtúpalẹ̀ (concatenative morphology) àti ìjẹyọ wúnrẹ̀n gírámà aṣemọ́fíìmù kọ́ńsónàǹtì aránmúpè aṣesílébù (KAA) (/m/n/). Tíọ́rì ìmọ̀ ẹ̀da-èdè tí a lè lo láti ṣe èyí ni'tíọ́rì abìpele tàbí adápelení' (Oyèbádé 2005:85) ló dábàá ẹ̀dà orúkọ yìí. Tíọ́rì yìí ni Pulleybank (1983) pè ní Autosegmental theory. Kókó èrò méjì ló mú kí tíọ́rì yìí gbayì:

12(i).Pe ìpelee-ohùn àti ìpele ègé-ìró wa lọ́tọ̀ọ̀tọ̀. Ìyẹn ni pé òfin lè ṣiṣẹ́ ní ìpele kan láìkan ìpele kejì.

(ii)Tíọ́rì yìí fẹ àlàyé nípa agbára tàbí òmìnira àwọn àbùdá kọ̀ọ̀kan láti dá dúró lojú. Èyí jẹ́ kókó kan lára èrò tíọ́rì onídarọ̀ ti Chomsky (1986) tọ́ka sí. Tíọ̀rì abìpele gbà pé a lè pa odidi ìró jẹ ṣùgbọ́n kí àwọn àbùdá kan tàbí méjì nínú àbùdá ìró tí a pa jẹ má pòórá pẹ̀lú ìró náà (Feature stability) – èyí tó túmọ̀ sí ìgbòmìnira Àbùdá.

Ní àkọ́kọ́, ẹ jẹ́ kí a gbójú kúrò lára àmì ohùn orí wọn. Òfin fonọ́lọ́jì abìpele fàyè gba èyí. Ẹ̀wẹ̀, gẹ́gẹ́ bí Oyèbádé (1998) àti (2005) ṣe mẹ́nu bá á nínú àlàyé nípa fonọ́lọ́jì onídàrọ, ẹ̀ka tíọ́rì onídàrọ gbà pe àpapọ̀ àwọn àbùdá ló ń di fóníìmù kọ̀ọ̀kan. Èyí pe àkíyèsí wa sí àsọtẹ́lẹ̀ pé àbùdá kọ̀ọ̀kan ní agbára ìṣèjọba adáwà ṣáájú àkànpọ̀ wọn. Nítorí náà, a lè pa àwọn àbùdá kan jẹ kí àbùdá mìíràn dúró. Àwọn àbùdá tó bá dúró yìí tún lè kópa nínú ìgbésè fonọ́lọ́jì tó bá wáyé ní ọ̀gangan tí wọn ti jẹyọ.

Ní báyìí, ẹ jẹ́ kí a wo àbùdá awonú (inherent features) àwọn fóníìmù un àti in.

| | [un] | [in] |
|---|---|---|
| 13. | +aṣesílébù | +aṣesílébù |
| | + ìránmú | + ìránmú |
| | + ẹ̀yìn | + iwájú |
| | + ahánupè | + ahánupè |
| | + fáwẹ̀lì | + fáwẹ̀lì |

Tí a bá wo àwọn àbùdá máràárún yìí dáadáa, a ó rí i pé àwọn àbùdá mẹ́tẹ̀ẹ̀ta àkọ́kọ́ – aṣesílébù, ìránmú, ẹ̀yìn/iwájú jẹ́ àbùdá tó ṣe pàtàkì ju méjì yòókù lọ – ìyẹn ahanupe àti fáwẹ̀lì tó gbẹ̀yìn. Èyí rí bẹ́ẹ̀ nítorí àbùdá aṣesílébù tí sọ àsọtẹ́lẹ̀ nípa àbùdá fáwẹ́lì. Tí ìpajẹ bá kan àwọn àbùdá méjì tó kẹ́yìn wọ̀nyí – ahánupè àti fáwẹ̀lì, àwọn àbùdá yóòkù yóò jẹ:

| | [un] | [in] |
|---|---|---|
| 14. | + aṣesílébù | + aṣesílébù |

+ ìránmú + ìránmú
+ ẹ̀yìn + iwájú

Ìpajẹ àwọn àbùdá méjì tó gbẹ̀yìn – àhánupè àti fáwẹ̀lì, ti kó bá àbùdá kíkún un àti in. Nítorí náà, kò ṣe é ṣe fún wọn láti lè dá dúró gẹ́gẹ́ bí odidi fóníìmù mọ́. Àwọn àbùdá mẹ́tẹ̀ẹ̀ta – aṣesílébù, ìránmú, ẹ̀yìn/iwájú ló ní àwọn àmì tàbí ìró tí a máa ń fi pa àrokò fún wọ́n, b.a.

(a) Aṣesílébù

Àmì tàbí ìró tó jẹ́ àrokò fún àbùdá aṣesílébù ní èdè Yorùbá ni àmì-ohùn. Ìdí nìyí tó fi jẹ́ pé iye àmì-ohùn tó bá jẹyọ nínú ọ̀rọ̀ tàbí ìpèdè èdè Yorùbá ni iye sílébù tó wà níbẹ̀.

(b) Ìránmú

Àmì tàbí ìró tó ń ṣe àfihàn fún àbùdá ìránmú ní èdè Yorùbá ni m tàbí n. Ohun tó fa èyí ni pé m jẹ́ àrokò fún àmì àbùdá ìránmú tó tún gba àbùdá ẹ̀yìn tàbí roboto nígbà tó jẹ́ pé n jẹ àmì fún àbùdá ìránmú tó tun gba àbùdá iwájú tàbí pẹrẹṣẹ. Nítorí náà, àkópọ̀ àbùdá – aṣesílébù, ìránmú, ẹ̀yìn – yóò yọrí sí àmì àrokò m nígbà tí àkópọ̀ àbùdá – aṣesílébù, ìránmú, àti iwájú – yóò yọrí sí àmì àrokò n.

Ẹ̀wẹ̀, níwọ̀n bí ó ti jẹ́ pé èdè Yorùbá kò fàyè gba ìsùpọ̀ ìró kọ́ńsónàǹtì, tí ó sì jẹ́ pé àrokò m tàbí n náà ló dúró fún ìró-ìfọ̀ [m] àti [n] nínú èdè Yorùbá – àwọn ẹ̀ka-èdè Yorùbá kan lè lo òfin àfikún gẹ́gẹ́ bí èrò Awóbùlúyì (1996) nípa fífi fáwẹ̀lì ikún KAA tí àrokò wọ́n jẹ́m àti n láti mú kí ìhun ọ̀rọ̀ lè jẹ́ aṣeégbà. Lára àwọn ẹ̀ka-èdè tó yan ìgbésẹ̀ yìí ni Ifẹ̀, Ìjẹ̀ṣà àti Mòbà. Fáwẹ̀lì i àfikún yìí yóò gba àbùdá ìránmú àti aṣesílébù nínú àwọn ẹ̀ka-èdè bẹ́ẹ̀.

Ohun tí àbá yìí ń sọ ni pé:

15(i) a pa un tàbí in jẹ

ii. méjì nínú àwọn àbùdá yìí ko pòórá. Àbùdá méjì náà ni: aṣesílébù àti ìránmú.

iii. n dúró fún fóònù aṣàfihàn àbùdá aránmú

iv. n lè yí padà di m ti ìró kọ́ńsónàǹtì apá-ọ̀tún bá ní àbùdá ajẹmétè-tí fáwẹ̀lì àyanupè kò sí jẹ yọ nínú ìhun sílébù rẹ̀ tàbí tó bá jẹ́ pé un ni ìró ìpìlẹ̀ tó para dà di m. Èyí ló fà á tí un (AR ẹnìkínní aṣolùwà, ẹyọ) fi máa ń di mi nínú àwọn ẹ̀ka-èdè Yorùbá kan bí ẹ̀ka-èdè Èkó. Òfin àfikún ló sọ m di mi.

v. Àwọn ẹ̀ka-èdè kan lè yàn nínú ìtàn ìdàgbàsókè èdè Yorùbá láti fi fáwẹ̀lì i mọ́n tàbí m pẹ̀lú èròǹgbà àti yanjú òfin ìdìpọ̀ kọ́ńsónàǹtì (ẹ̀ka-èdè Ifẹ̀ jẹ́ ọ̀kan níbẹ̀).

## Ìkádìí

A tí gbìyànjú nínú iṣẹ́ ìwádìí yìí láti ṣe àfihàn àwọn ẹ̀yà gbólóhùn onítunmọ̀ abèjì méjì nínú ẹ̀ka-èdè Ifẹ̀. A kíyèsîí pé orísi gbólóhùn ìyísódì abèjì méjì ni ó wà nínú ẹ̀ka-èdè Ifẹ̀. Ìlò atọ́ka tàbí wúnrẹ̀n ìyísódì méjì nínú àwọn gbólóhùn mìíràn máa ń yọrí sí ìtumọ̀ ìjọ́hẹn nígbà tí ó jẹ́ pé ìlò atọ́ka ìyísódì méjì ní ìgbà mìíràn tún máa ń yọrí sí ìtumọ̀ ìjọ́hẹn. Ní àfikùn, àbọ̀ iṣẹ́ ìwádìí yìítún ṣe àfihàn àwọn gbólóhùn kan èyí tí ó jẹ́ pé atọ́ka ìyísòdì kan jẹyọ nínú ìhun wọn. Dípò tí àwọn

gbólóhùn yìí ìbá fi nì ìtumọ̀ òdì, ìtumọ̀ ìjọ́jẹn ni wọ́n ní. A kíyèsíi pé àwọn ọ̀rọ̀-ìṣe tàbí ẹ̀pọ́n ọ̀rọ̀-ìṣe onítumọ̀ òdì ni ọ̀pọ̀ tí ó wà nínú ìlànà ìṣẹ̀dá ọ̀rọ̀ orúkọ tí ó súyọ nínú ìhun wọn gẹ́gẹ́ bí olùwà tàbí àbọ̀. Lára irú àwọn ọ̀rọ̀ orúkọ wọ̀nyí ni, àjẹ̀kù, àṣetì, àghámọ, òdì, adití abbl.

Tí àwọn ọ̀rọ̀ orúkọ yìí bá jẹyọ nínú gbólóhùn tí atọ́ka ìyísódì kan tì jẹyọ, ìtumọ̀ ìjọ́jẹn ní irú gbólóhùn bẹ́ẹ̀ yóò ní. Iṣẹ́ ìwádìí tún mẹ́nu bá ìhun ìpìlẹ̀ kọ́ńsònàǹtì áránmupè nínú ẹ̀kọ́ fọnọ́lọjì àti síńtáàsì èdè Yorùbá nípa ṣíṣe àfihàn *un* tàbí *in* gẹ́gẹ́ bí ìró fáwẹ̀lì tí ó ń parade di kọ́ńsónàǹtì aránmúpè aṣesílébù. A fìdíi rẹ̀ múlẹ̀ pé ìpàdánù àwọn àbùdá àdání kan nínú ìmọ̀ ìdàgbàsókè èdè ni ó fa Àtúnrọ èyí tí ó yọrí sí kọ́nsónáǹtì aṣeṣílébù nínú èdè Yorùbá. Á lérò pé àbọ̀ iṣẹ́ ìwádìí yìí yóò pé fún ìpènijà àwọn iṣẹ́ mìíràn lórí kókó iṣẹ́ ìwádìí yìí.

## ÀKÓJỌ ÌWÉ ÌTỌ́KASÍ


Abraham, R.C. (1958). *Dictionary of Modern Yorùbá London:* Hodder and Stoughton.

Adékúnlé, M.A. (2019). Ipa ètò ìpàárọ̀ ìró Fáwẹ́lì nínú Àṣàyàn àwọn Ẹ̀ka-èdè Yorùbá. *Yorúbá: The Journal of Yorùbá Studies Association of Nigeria*: 9/3: 142-158.

Adékúnlé, M.A. (2018). Fífi ìmọ̀ ẹ̀dá-èdè ṣe àtúpalẹ̀ ìyísódì nínú ẹ̀ka-èdè Ifẹ́. Ph.D. thesis, Department of Linguistics and Nigerian Languages, Ọlábísí Ọnàbánjọ University, Àgọ́-Ìwòyè, Ògùn State.

Adéníyì, O.G. (2019). Fífi Ojú ìṣẹ̀dá-ọ̀rọ̀ wo àwọn Ọ̀rọ̀-orúkọ aṣẹ̀dá nínú Ogún Ọmọdé tí Akínwùnmí Ìṣò.lá kọ. M.A. dissertation, Department of Linguistics and Nigerian Languages, Ọlábísí Ọnàbánjọ University, Àgọ́-Ìwòyè.

Adésiyan, R.A. (2014). "Ìtupalẹ̀ Àwọn Wúnrẹ̀n Onítumọ̀ Gírámà nínú Ẹ̀ka-Èdè Ìlàjẹ àti Ìjẹ̀bú". Ph.D. thesis, Deparment of Lingusitcs and African languages, Ọbáfẹ́mi Awólọ́wọ̀ University, Ilé-Ifẹ̀.

Adéwọlé, L.O. (2018a). Ọ̀rọ̀-orúkọ Aṣèbéèrè nínú Ẹ̀ka-èdè Ifẹ̀. Research in Languages and Literatures, Department of Linguistics and African Languages, Ọbáfẹ́mi Awólọ́wọ̀ Univerity, Ilé-Ifẹ̀.

Adéwọlé, L.O. (2018b). "Oyèláràn and the localist on the sources of the Yorùbá Progressive". Research in Yorùbá Languge and Literature 13:56-64.

Adéwolé, L.O. (2011). "Àtúnyẹ̀wò Arópọ̀-orúkọ nínú Ẹ̀ka-èdè Ife. *Láàńgbàṣà*. Department of African and Asian Languages. University of Lagos, Lagos 15: 4-13.

Adéwọlé, L.O. (2000). Negation in Ifẹ̀ Dialect: A Yorùbá Dialect. *Journal of Asian and African Studies* (Tokyo, Japan). 58: 397-403.

Archangeli, D. and D. Pulleyblank (1989). Yorùbá Vowel Harmony. *Linguistics Inquiry*, 20/2: 173-218.

Awóbùlúyì (2014). Yorùbá kò gbọ́dọ̀ kú. *Ìdánilẹ́kọ̀ọ́ Gbogbogbò, Ẹ̀ka Ìmọ̀ Áàtì,*Yunifásítì Ọbáfẹ́mi Awólọ́wọ́, Ilé-Ifẹ̀ (Ọjọ́bọ̀, ọjọ́-kẹfà, oṣù Ìrèlé, 2014).

Awóbùlúyì, O. (2013). *Ẹ̀kọ́ Gírámà Èdè Yorùbá.* Òṣogbo: Atman Limited.

Awóbùlúyì, O. (1998). Àwọn ẹ̀ka-èdè Yorùbá. Presented at Annual conference of the Yorùbá Studies Association of Nigeria (YSAN) held in Ìbàdàn Pastoral Institute, Ibadan (Nov. 24-26).

Awóbùlúyì, O. (2008). *Ẹ̀kọ́ Ìṣẹ̀dá-Ọ̀rọ̀ Yorùbá* Àkúrẹ́: Montem Paperbacks.

Awóbùlúyì, O., Àti O., Oyèláràn (2017). *Ìwé Ìléwọ́ Ìkọ̀wé Yorùbá Òde-Òní.* Ìlọrin: Kwara State University Press.

Bámgbóṣe, A. (1990). *Fonọ́lọ́jì àti Gírámà Yorùbá.* Ìbàdàn: University Press.

Cann, R. (1986). The structure of words. *Work in Progress* 19:107-121, Edinburgh: Department of Linguistics, University of Edinburgh.

Dairo, O.L. (2015). Man, Language and Identity: Linguistics Consideration for National Development. *71st Inaugural Lecture.* Ọlábísí Ọnàbánjọ University, Àgọ́-Ìwòyè (Tuesday, June 9, 2015).

Fábùnmi, F.A. (2006a). *Aṣèrànmọ́ Ọ̀rọ̀-ìṣe nínú Yorùbá Ìjẹ̀ṣà.* Ilé-Ifẹ̀: Ọbáfẹ́mi Awólọ́wọ̀ University Press.

Fábùnmi, F.A. (2006b). "Àsìkò àti Ìbá-Ìṣẹ̀lẹ̀ nínú Ẹ̀ka-Èdè Mọ̀fọ̀lí", Ph.D. thesis, Department of Linguitics and African Languages, Ọbáfẹ́mi Awólọ́wọ̀ University, Ilé-Ifẹ̀.

Gazdar, G.E. Kelin, G. Pullum and I. Sag (1985). *Generalized Phrase Structure Grammar.* Oxford: Basil Blackwell.

Goldsmith, J. (1976). "An Overview of Auto-Segmental Phonology". *Linguistic Inquiry* 2(i): 23-68.

Owólabí, K. (2011). *Ìjìnlẹ̀ Ìtúpalẹ̀ Ède . . . Fónẹ́tíkì àti Fonọ́lọ́jì Èdè Yorùbá* (Àtúnṣe Kejì). Ìbàdàn: Akada Publishers.

Oyèbádé, F.O. (2005). "Àwọn Tíọ́rì Fonọ́lọ́jì àti Èdè Yorùbá" Adéníyì, H àti A. Òjó (el). *Ìlò-Èdè àti Ẹ̀ka-Èdè Apá Kejì* o.i. 76-97.

Oyèbádé, F.O. (1998). *A Course in Phonology*. Ìjẹ̀bú-Òde: Shebiotimọ Publications.

Rájí, L.O. (2017). Lílo ìmọ̀ Ìṣẹ̀dá-ọ̀rọ̀ fún Ìtúpalẹ̀ *Saworoidẹ* tí akínwúnmí ìṣọ̀lá kọ. M.A. dissertation, Department of Linguistics and African Languages, Ọbáfẹ́mi Awólọ́wọ̀ University, Ilé-Ifẹ̀.

Táíwò, O. (2011). *Mofọ́lọ́jì.* Ìbàdàn: Akadá Publishers.